# LILỌ KURO NI OKE SINAI

## Numeri 9:15-23; 10:11-13, 29-36

## ẸKỌ 91 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Awa nṣí lọ si ibi ti OLUWA ti wi pe, Emi o fi i fun nyin: wá ba wa lọ, awa o ṣe ọ li ore: nitoripe OLUWA sọ̀rọ rere nipa Israẹli" (Numeri 10:29).**

**I Ami Awọsanma**

1. Ọwọ̀n awọsanma lọsan ati ọwọ́n iná loru n tọ iṣisẹ wọn lọ, Numeri 9:15-23; 10:11; Ẹksodu 13:21, 22; 14:19, 20, 24, 25; 40:34-38; Orin Dafidi 78:14; 105:39; Isaiah 4:5, 6
2. Ọwọ̀n awọsanma ká kuro, awọn Ọmọ Israẹli si ṣí kuro ni Sinai, Numeri 10:12, 33, 34; Deuteronomi 32:11, 12
3. Ọwọ̀n awọsanma duro, Israẹli si pagọ ni Parani, Numeri 10:12, 13, 33, 34

**II Mose Nawọ́ Ipè si Àna Rẹ̀**

4. "Wá ba wa lọ," Numeri 10:29; Isaiah 55:1-3; Johannu 7:37; Ifihan 22:17
5. Awọn nnkan ti ayé ni idè ti o de Hobabu mọlẹ, Numeri 10:30; Matteu 19:21, 22
6. Afo kan ṣi ṣilẹ ti Hobabu i ba dí, Numeri 10:31; I Kọrinti 12:8-27
7. Ere n duro de Hobabu, Numeri 10:32; I Kọrinti 2:9

**III Adura Owurọ ati ti Aṣaalẹ**

8. "Ki a si tú awọn ọtá rẹ ká, Numeri 10:35
9. "Pada, OLUWA, sọdọ ẹgbẹgbarun awọn enia Israẹli," Numeri 10:36

## ALAYE

**Igba Kikọ́ Ẹ̀kọ́**

O fẹrẹ to ọdun kan ti awọn Ọmọ Israẹli fi wà ni Oke Sinai. Ni akoko yii ni awọn eniyan naa gba ofin lati ọwọ Ọlọrun nipa eyi ti a oo fi ṣe akoso wọn ni Ilẹ Ileri. Wọn lo akoko naa daradara bi wọn ti wà papọ fun idanilẹkọọ si ipa ti Ọlọrun. Nihin ni wọn kan Apoti Majẹmu, ti wọn gbé Agọ Ajọ duro, ti Oluwa fun wọn ni ipò oyè alufaa ti wọn si kọ́ ẹkọ nipa ọna ti Ọlọrun fẹ ki wọn gbà sin Oun.

**Ọwọ̀n Awọsanma**

Ifarahàn Ọlọrun wa lori Agọ Ajọ gẹgẹ bi ọwọ̀n awọsanma lọsan ati gẹgẹ bi ọwọ́n ina loru. Nigba ti Ọlọrun ba fẹ́ ki Israẹli tẹ siwaju, ọwọ̀n awọsanma nì a ṣí kuro lori Agọ-Ajọ, a si maa lọ niwaju wọn. Niwọn igba ti ọwọ̀n awọsanma bá duro lori Agọ-ajọ Israẹli a wà ni ibudo ti wọn pagọ si, i baa ṣe fun ọjọ meji, oṣu kan, tabi ọdun kan (Numeri 9:15-23). Lai ṣe aniani, nigba miiran irin-ajo naa maa n mú aarẹ wá, nigba ti o si ṣe pe nigba miiran diduro pẹ́ titi ni ibudo kan a sú awọn Ọmọ Israẹli, ṣugbọn Ọlọrun ni Aṣiwaju wọn. Ki i ṣe gbogbo igba ni Onigbagbọ́ maa n mọ ki ni idi ti Ọlọrun fi dari oun lọna kan tabi omiran, ṣugbọn awọn ti o ba tẹle itọni Rẹ̀ maa n ri ère kikún gbà. Ni ọpọlọpọ igba Ọlọrun a sé ọna mọ́ awọn eniyan rẹ̀ bi o tilẹ ṣe pe wọn kò ri ewu ti o wà niwaju. Igba miiran ẹ̀wẹ̀ Ọlọrun a paṣẹ titẹ siwaju fun awọn eniyan Rẹ̀ nigba ti wọn kò ri idi ti wọn fi ni lati ṣí ẹsẹ̀ rara. Filippi ajihinrere ni Oluwa pe kuro nibi isọji nla kan ni Samaria lati dori kọ ọna ijù, ṣugbọn Ọlọrun ni idi fun ṣiṣe bẹẹ: ọkàn kan ti oungbẹ n gbẹ n wá Ọlọrun (Iṣe Awọn Apọsteli 8:26-40).

**Titẹ Siwaju**

Nisisiyii ni akoko tó lati lọ siwaju ninu irin-ajo naa. Ọlọrun fi ami hàn bẹẹ. Ọwọ̀n awọsanma ti ṣí kuro lori Agọ-ajọ. Itẹsiwaju ti bẹrẹ ni apa iha ila-oorun ibudo lẹsẹkẹsẹ ti wọn ti gbé ọpagun Juda soke (asia ti wọn le ri loke lati ọna jijin réré) ti ẹya wọn si bẹrẹ irin bi ẹgbẹ ogun nla. Awọn ẹya ti o tún tẹle wọn ni Issakari ati Sebuluni ti a kó pọ̀ mọ́ ẹya Juda labẹ ọpagun rẹ̀ lati jẹ́ ẹgbẹ́ kan. Bi eyi ti n ṣẹlẹ lọwọlọwọ, awọn ọmọ Lefi ti n tú Agọ-ajọ, wọn n mura lati tẹ̀ siwaju. Awọn idile Gerṣoni ati Merari (ninu ọmọ Lefi) tẹle ẹgbẹ ti Juda pẹlu ẹrù awọ, aṣọ, igi ati òpó Agọ-ajọ ki wọn le tete gbe e duro nibikibi ti wọn yoo bá tẹdo si.

Lati iha guusu ibudo ni ẹgbẹ́ ti Reubẹni ti dide pẹlu ọpagun wọn ti n fẹ́ lẹlẹ, wọn si ṣẹri biri gba ọwọ ọtun la aarin ibi ti Juda ti pagọ si kọja. Lẹyin ẹya Rẹubẹni ni a ri idile Kohati ti awọn ti Apoti Majẹmu ati awọn ohun-elo Ibi Mimọ́. Bi wọn ṣe n de ibi ti wọn yoo tun tẹdo si a o ti gbe agọ duro. Lati iha iwọ-oorun ni ọpagun Efraimu ti ṣẹ́ yọ pẹlu ẹgbẹ́ ti wọn, wọn rin la ibudo já ni ọ̀kánkán taara, bakan naa, ni a ri ọpagun Dani loke ni iha ariwa, wọn dari si ọwọ́ òsì, awọn ni o si kadii gbogbo ijọ Israẹli.

Bawo ni iran yii yoo ti gbadun tó lati wò lati ori Oke Sinai, ẹgbẹẹgbẹ ogun Israẹli nla bi wọn ti n tò kọja lọ́wọ̀ọwọ́ -- ọgbọ̀n ọkẹ ọkunrin (600,000) lai ka obinrin ati awọn ọmọde! Nihin a tun ri i pe Ọlọrun jẹ́ Ọlọrun eto, ki i ṣe olupilẹṣẹ̀ ohun rudurudu.

**Opin Kan**

Ni akoko naa ti ibudo Israẹli kún fún iṣẹ́ ati igboke-gbodo bayii, Mose sọ fun Hobabu ana rẹ̀ pe "Awa nṣí lọ si ibi ti OLUWA ti wi pe, Emi o fi i fun nyin." Mose ati Israẹli n rìn lọ si ibi kan ti o daju. Ọlọrun ṣeleri fun wọn pe Oun O fun wọn ni ilẹ̀ kan.

Awa, naa, pẹlu ni ileri ilu kan ti ó dara jù bẹ́ẹ̀ lọ. "Ṣugbọn nisisiyi nwọn nfẹ ilu kan ti o dara jù bẽ lọ, eyini ni ti ọ̀run: nitorina oju wọn kò ti Ọlọrun, pe ki a mã pe On ni Ọlọrun wọn; nitoriti o ti pèse ilu kan silẹ fun wọn" (Heberu 11:16). Iwọ ha wà ṣá ninu ayé, ni irinke-rindo lasan lai ni opin kan ti o daju lati lepa, lai ni idaniloju iyè ainipẹkun?

Ronu bi igbesi-ayé bẹ́ẹ̀ ti jẹ́ alainilaari tó! Ọmọ Ọlọrun ní opin kan ti ó n lepa, ó ni ileri kan ti ó rọ̀ mọ́, ó si ní Amọna kan lati ràn án lọwọ titi dé Ilu naa ti Ọlọrun ti pèse silẹ.

"Wá ba wa lọ, awa o ṣe ọ li ore: nitoripe OLUWA sọ̀rọ rere nipa Israẹli." A kò gbọdọ lọra lati pe ẹnikẹni lati bá wa kalọ si ọna igbala yii nitori Oluwa ti fi "ileri rẹ̀ ti o tobi pupọ ti o si ṣe iyebiye fun wa"(2 Peteru 1:4). A oo ni "ọrun titun ati aiye titun ninu eyiti ododo ngbé." Bi awọn Farisi ba lè "yi òkun ati ilẹ ká lati sọ enia kan di alawọṣe," ti wọ́n si sọ ọ́ di ọmọ ọrun-apaadi nigba meji ju ara wọn lọ, kò ha yẹ ki awa ọmọ Ọlọrun tubọ ni itara lati yọ ọ̀pọ ọkàn kuro ninu ẹ̀ṣẹ? Bi a ti jẹ́ ajogun Ọlọrun ati ajumọ-jogun pẹlu Kristi, a ha n lọra sibẹ lati pe awọn ẹlẹgbẹ wa pé ki wọ́n bá wa kalọ?

**Idè Ayé**

"On si wi fun u pe, Emi ki yio lọ; ṣugbọn emi o pada lọ si ilẹ mi, ati sọdọ ará mi." Idè ayé kò rọrun lati já kuro. Awọn ohun pupọ ni o lè so wá pọ̀ mọ́ ayé yii bi a kò bá ti i rí iran Ọrun. Nigbakuugba ni a n gbọ́ pé, "ohun pupọ wà fun mi ti n kò lè fi silẹ." Eyi rán ni leti ọmọdekunrin kekere kan ti a fẹ́ fún ni kẹ̀kẹ́ titun kan dipo fere ti ó fi n ṣire. Ọmọde naa n fẹ́ kẹ̀kẹ́ yii ni tootọ ṣugbọn kò fẹ́ fi fèrè rẹ̀ silẹ, ó si kọ kẹ̀kẹ́ ti a fẹ́ fi fun un. Lọjọ oni, awọn eniyan n fi ọwọ́ rọ́ iyè ainipẹkun tì sí apá kan nitori awọn ohun ìní ayé ti kò ni èrè rara fun gẹgẹ bi fere ti a fi òjé lasan ṣe.

Mose "kò gba" awawí Hobabu, ṣugbọn ó fi hàn án pé àyè wa fún un lati dí. Ayè pupọ ni ó wà fun awọn alagbaṣe ninu Ijọba Ọlọrun. Jesu wi pé, "Ikore pọ̀, ṣugbọn awọn alagbaṣe ko to nkan" (Luku 10:2). Mose ṣe ileri fun Hobabu pé, "Orekore ti OLUWA ba ṣe fun wa, on na li awa o ṣe fun ọ." Jesu ṣe ileri pé, "Ẹniti nkore ngbà owo ọ̀ya, o si nkó jọ si iye ainipẹkun" (Johannu 4:36).

**À n Fẹ́ Alakoso**

Ọlọrun ni ó n ṣe Amọna Israẹli nipa ọwọ̀n awọsanma ati ọwọ̀n iná, sibẹ Mose rọ Hobabu lati jẹ́ ojú fun wọn. Bi Ọlọrun ni yoo bá ṣe akoso wọn, ki ni wọ́n n fẹ́ fi ojú Hobabu ṣe? Awọn ẹlomiran rò pé eyi fi hàn pé Mose kò ni igbẹkẹle ninu Ọlọrun. A kò lè rò bẹ́ẹ̀ rara. Ohun pupọ ni ẹni ti o ti ni iriri aginju ti wọ́n wà yii lè tọka sí, bi ibi ti koriko tútù yọ̀yọ̀ fun ounjẹ ẹran gbé wà, ibi ti omi wà, awọn agbegbe ti ó kún fún ewu, ati ibi ti wọ́n ti lè ri nnkan èlò fun iná dídá, ni ibikibi ti Ọlọrun bá yàn fun Israẹli lati duro ki wọn si pagọ. A kò le ṣai ni awọn alakoso ati awọn alabojuto ti wọ́n kún fun imọ̀ ati ọgbọ́n Ọlọrun, bi o tilẹ jẹ́ pé Ẹmi Ọlọrun n tọ́ wa sibẹ.

**Taa ni Yoo Lọ**

Njẹ Hobabu bá Israẹli lọ? Ki ni idahun ti rẹ sí ipè Ihinrere? Iwọ yoo ha kọ ipè naa, nigba ti o ṣe pé, "ohun ti oju kò ri, ati ti etí kò gbọ, ti kò si wọ ọkàn enia lọ, ohun wọnni ti Ọlọrun ti pèse silẹ fun awọn ti o fẹ ẹ" (1 Kọrinti 2:9).

**WÁ BÁ WA KALỌ**

**Ọkunrin Midiani kan**
**Ti Oluwa fẹ́ lò**
**Tọ Israẹli wá laginju.**
**Mose bẹ̀ ẹ́ pé, "Ba wa kalọ, 'wọ o ri 're**
**Ileri rere wà fun Israẹli"**

**Egbe:**

**Ba wa kalọ, a o ṣe ọ loore**
**Pin ninu ilẹ wara at'oyin naa**
**Ba wa lọ si ilẹ Kenaan**
**Wá gba ayọ̀ pupọ lọfẹẹ.**

**Ilẹ 'leri yii ni awa fẹ lọ**
**Oluwa ni Ọgagun wa**
**A ó ja 'ja ṣẹgun**
**Ilẹ naa dara, omi on oke wà nibẹ**
**Ti Ọlọrun n tọju lojoojumọ**

**Eyi ni a wi fun gbogbo eniyan**
**Wá kalọ, Jesu wà fun gbogbo wa**
**Wá si ẹgbẹ́ wa!"**
**Si gbogbo ẹni ti aarẹ ti mu pẹlu**
**"Ba wa kalọ silẹ Beula rere yii."**

**AWỌN IBEERE**

1. Wá gbogbo ẹsẹ Iwe Mimọ ti o sọ nipa ọwọ̀n awọsanma ni aginju.

2. Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ti pẹ́ tó ni Oke Sinai?
3. Ṣe akọsilẹ gbogbo anfaani ti o wà ninu jijẹ́ ipè Ihinrere.
4. Ere wo ni eniyan le jẹ nipa kikọ ipè naa?
5. Ki ni o kà ninu Bibeli nipa ki eniyan jẹ ki ide ẹbi de oun molẹ ki o má le tẹle Jesu?
6. Ṣe Mose n fẹ ki Hobabu maa ba Israẹli wá ibi ti wọn yoo duro pagọ si ni?
7. Njẹ iwọ ri si i pe ki ẹni kọọkan maa fun awọn eniyan ni ipè Ihinrere? Bi ó ba tọna, ewo ni o n ṣe nipa rẹ̀?
8. "Rere" wo ni Oluwa ti sọ nipa Israẹli?
9. Ki ni Mose maa n ṣe lowurọ ati ni aṣaalẹ?
10. Bawo ni Israẹli ṣe n mọ̀ pe akoko to fun wọn lati palẹ agọ wọn mọ́?